# Ipa Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Ìgbàlódé lórí Ìtànkálẹ̀ àti Ìdàgbàsókè Orin Ìbílẹ̀ Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin

**Hakeem Ọláwálé,** ***Ph.D.***
*Department of Linguistics and African Languages*
*Kwara State University, Màlété*
*hakeemolawale4@gmail.com*

## Àṣamọ̀

*Ọ̀kan pàtàkì lára orin ìbílẹ̀ Ìlọrin tó jẹ́ ajẹmábo-jẹ-máàfin ni orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin jẹ́. A tilẹ̀ tún lè pè é ní ajẹmágbà nítorí pé àwọn àgbàlagbà obìnrin tó jẹ́ ẹbí àti ìyàwó ní ìdílé ọba Ìlọrin ló máa ń kọ ọ́. Lóòótọ́, a kò lè ṣàfẹ́kù ìkópa àwọn ọ̀ṣọ́ọ́rọ́ adélébọ̀ náà nibẹ̀ láti máa fojú sí i àti láti gbe orin náà, ṣùgbọ́n àwọn àgbàlagbà obìnrin tí ọjọ́ orí wọn ti lé ní ọgọ́ta ọdún ló wọ́pọ̀ nínú kíkọ orin náà. Àwọn tó jẹ́ ẹbí ọba Ìlọrin nìkan ni wọ́n ni orin yìí tí wọ́n sì fi máa ń yẹ́ ara wọn sí pàápàá jùlọ tí ọmọ ọba Ìlọrin kan bá ń ṣe ìgbéyàwó, yálà ó jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin. A ṣàkíyèsí pé iṣẹ́ ìwádìí kò fi bẹ́ẹ̀ sí lórí orin yìí nítori pé wọn kìí gba àjòjì láàyè láti kópa níbẹ̀ débi tí yóò farabalẹ̀ máa ká eré wọn sílẹ̀. Èyí ló mú wa lọ gba ìyọ̀nda lati ààfin Ọba Ìlọrin gẹ́gẹ́ bí oníṣẹ́-ìwádìí, tí ó sì fún wa ní àǹfààní láti bá wọn kópa níbi òde orin wọn àti ṣíṣe ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò tó kún. A ká wọn sínú ẹ̀rọ, a ya fọ́tò wọn, a sì tún rí orin wọn tó wà nínú fọ́nran díẹ̀ lára ìgbéyàwó tí wọ́n ti ṣe tẹ́lẹ̀ gbà láti ṣe àdàkọ fún ìtúpalẹ̀. Kókó pàtàkì tí iṣẹ́ yìí gùnlé ni àgbéyẹ̀wò àwọn iṣẹ́ pàtàkì tí wọ́n ń fi orin ólọ́mọ-ọba yìí jẹ́ láwùjọ Ìlọrin pẹ̀lú ipa pàtàkì tí onírúurú ọ̀nà ìbára-ẹni-sọ̀rọ̀ àti ti tọ́rọ́-fọ́n-kálé òde-òní ń kó lórí ìdàgbàsókè rẹ̀.Tíọ́rì Ajẹmọ́-àṣà-ìbílẹ̀ àti tíọ́rì Ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ni a fi ṣàtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí. Àbájáde iṣẹ́ yìí tànmọ́lẹ̀ sí i bó ṣe ṣe pàtàkì tó kí a máa mú ìgbélárugẹ bá àwọn nǹkan àṣà ìbílẹ̀ wa*

*gbogbo nípasẹ̀ ìṣàmúlò àwọn ohun èlò ìgbàlódé oríṣìíríṣìí kí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn nǹkan àjogúnbá wa má baà dohun ìgbàgbé, kí àmúgbòòrò àtí ìtẹ̀síwájú lè máa bá wọn, kó sì tún wúlò fún àwọn ìran tó ń bọ̀.*

**Kókó Ọ̀rọ̀**: Ajẹmábo-jẹ-máàfin, Orin Ìbílẹ̀, Ọlọ́mọ-Ọba-Ìlọrin, Ajẹmágbà, Ìgbéyàwó

## Ìfáárà

Ọ̀tọ̀lórìn ni orin yìí ní àwùjọ àwọn Ìlọrin nítori pé àwọn àbùdá tó rọ̀ mọ́ ọn ṣàfihàn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àso tí kò ní irú kejì bí Ìlọrin ṣe tóbi tó. Ìdí ni pe ẹgbẹ́ orin yìí kan péré ló wà ní Ìlọrin, ó sì jẹ́ ti ẹbí ọba Ìlọrin nìkan.  Ó yàtọ̀ sí bí orin dàdàkúàdà, orin bàlúù, orin kàkàki/bẹ̀ǹbẹ́ tí wọ́n ní oríṣìí ẹgbẹ́ olórin tí wọ́n mọ̀-ọ́n-mọ̀ dá sílẹ̀ fún ìgbélárugẹ àṣà Ìlọrin àti láti rí oúnjẹ òòjọ́ wọn. Àwọn àgbàlagbà obìnrin tó jẹ́ ẹbí tàbí ìyàwó ní ìdílé ọba Ìlọrin ló máa ń kọrin náà. Orin Ọlọ́mọ-Ọba jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára orin ìbílẹ̀ Ìlọrin. Kódà òun ni a fẹ́rẹ̀ẹ́ lè pè ní àgbà láàrin àwọn onírúurú orin ìbílẹ̀ Ìlọrin nítorí pé ìdílé Ọba nìkan ni ó ni ín. Àwọn ọmọ ilé ọba nìkan ni wọ́n máa ń fi orin yìí yẹ́ sí lọ́kùnrin àti lóbìnrin pàápàá jù lọ tí wọ́n bá fẹ́ ṣe ayẹyẹ ìgbéyàwó.

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe gbọ́ ọ lẹ́nu ìyá àgbà tó jẹ́ olórí orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin, Àlàájà Ṣàdíà Èjìdé Alégẹ ní agboolé Alégẹ, ẹni ọ̀gọ́rùn-ún ọdún ó lé díẹ̀, tó ń gbé ní òpópónà Pópó Ọlọ́mọ-Ọba ní àdúgbò Bàábòkò Ìlọrin, ó ní láyé Ọba Shíttà (Ṣítà) tó jẹ́ ọba kejì ní Ìlọrin ni orin náà ti bẹ̀rẹ̀. Ọba Shíttà ló bí Sulayman tí òun náà sì jogún kí wọ́n máa kọ orin yìí lásìkò rẹ̀ títí di òní yìí. A tún rí i gbọ́ pé, tí ọba tuntun bá gorí oyè ní ìlú Ìlọrin wọ́n máa ń ṣe eré yìí láti fi yẹ́ àwọn ọmọ ọba sí àti láti fi máa rántí àwọn

ọba tó ti wàjà pẹ̀lú ipa takuntakun tí wọ́n ti kó nígbà tí wọ́n wà lóyè. Ìwádìí tún fi yé wa pé tí ọmọ Ọba bá bímọ tó bá wù ú tó bá pe eléré Ọlọ́mọ-Ọba láti wá ṣe eré fún un, àwọn máa ń lọ. Gẹ́gẹ́ bí àlàyé rẹ̀, ó ní agbègbè tí kò fi bẹ̀ẹ̀ jìnnà sí ààfin Ọba Ẹ́míà (Emir) Ìlọrin ni àwọn ti máa ń ṣeré nítorí pé àwọn kò gbọdọ̀ jìnnà sí àdúgbò ààfin púpọ̀ jù láti ṣe eré náà gẹ́gẹ́ bí ìṣẹ̀dálẹ̀ orin náà. Ó fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé agbègbè ààfin, pàápàá jùlọ àwọn agboolé ẹbí ọba Ìlọrin tí gbogbo wọn kò jìnnà sí ààfin, ni àwọn ti máa ń ṣeré náà. Orin ààfin tó jẹ́ ti ẹbí Ọba Ìlọrin ni, kò sì gbọdọ̀ jìnnà sí ààfin.

Kókó-ọ̀rọ̀ pàtàkì kan nípa orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin ni pé níbi ìgbéyàwó ni wọ́n ti sáábà máa ń lo orin yìí jù; yálà ọmọ ilé Ọba Ìlọrin tó jẹ́ obìnrin tí wọ́n fẹ́ sìn lọ sílé ọkọ tàbí ọmọkùnrin tó fẹ́ gbéyàwó nílé ọba. Wọn kì í ṣeré yìí fún ẹni tí kò bá jẹ́ ẹbí ọba rárá nítorí pé orin ìbílẹ̀ yìí wà fún ẹbí ọba Ìlọrin nìkan. Orin ààfin ni. Wọn kì í ṣe àwo jáde lórí rẹ̀ gẹ́gẹ́ bó ṣe wà fún orin Dadakúàdá, Bàlúù,Wákà àti Sẹnwẹlẹ lóde òní. Orin yìí wà fún àyẹ́sí àwọn ìran ọba Ìlọrin nìkan ni. Àwọn àgbàlagbà tó jẹ́ arúgbó àti àwọn abílékọ tí ọjọ́-orí wọn bẹ̀rẹ̀ láti nǹkan bíi ọgọ́tá ọdún títí dé ọgọ́rùn-ún ọdún ni wọ́n máa ń ṣeré yìí. Àwọn kan yóò jókòó tí wọ́n bá ń kọrin yìí, nígbà tí àwọn kan yóò nàró tí wọ́n á sì máa pòòyì àwọn tó ń kọrin yìí. Wọ́n á sì máa gberin bí wọ́n bá ti ń pòòyì náà. Ẹni tó ń kọrin yóò wà lórí ìjòkó pẹ̀lú àwọn àgbà mìíràn lẹ́gbẹ̀ẹ̀gbẹ́ ara wọn. Àlàájà Ṣàdíà Èjìdé Alégẹ tún fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ẹni tó bá fẹ́ pe àwọn yóò ra obì ọgọ́rùn-ún tó yanjú, ìyẹn ni àwọn yóò pín ká gbogbo ilé ọlọ́mọ-osú ọba Ìlọrin láti sọ fún wọn pé eré wà, àti ọjọ́ tí àwọn yóò ṣe é, àti ibi tí àwọn yóò ti ṣe é. Nínú ìwádìí yìí kan náà ni a tún rí i gbọ́ pé

àwọn tí àwọn jẹ́ Fúlàní ọlọ́mọ-ọba Ìlọrin nìkan ni àwọn máa ń ṣeré yìí nítorí pé àwọn ẹ̀yà Fúlàní mìíràn tún wà bí i Fúlàní Dìmọ́jọ̀, Fúlàní Ìbílẹ̀, Fúlàní Oníwàrà àti àwọn Fúlàní Bòròró.

Lára ohun èlò tí wọ́n fi ń mú adùn bá orin yìí ni ìlù kànnàngó méjì, odó ńlá ńlá méjì tí a ti bomi sí inú rẹ̀ tí a sì da igbá dé omi náà àti igbá ẹrù ńlá méjì tí a dójú wọn délẹ̀. Odó kọ̀ọ̀kan ni èèyàn méjì méjì yóò jókòó tì tí wọ́n á máa fi igi lù wọ́n bí wọ́n bá tí ń kọrin tí yóò sì máa bá orin náà mu rẹ́gí rẹ́gí. Igbá ẹrù ńlá tí wọ́n dójú rẹ̀ délẹ̀ yìí náà ni èèyàn bíi mẹ́rin tún lè jókòó ti ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn, tí wọ́n yóò máa fi igi rébété kọ̀ọ̀kan tí wọ́n mú lọ́wọ́ lù ú. Tí wọ́n bá ń náwó fún wọn lójú agbo yìí, inú igbá náà ni wọ́n máa pawó sí. Bóyá èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé Fúlàní ni ìran wọn láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ni; bó tilẹ̀ jẹ́ pé ewé tí pẹ́ lára ọṣẹ, ó ti dọṣẹ, èdè Yorùbá ni wọ́n fi ń kọ orin náà, kì í ṣe èdè Fúlàní tàbí Haúsá rárá.

Nínú orin náà, Ọba ni wọ́n ń pe Ọba Ìlọrin. Wọn kì í sábà pe Ọba wọn ní Ẹ́mía, gẹ́gẹ́ bí àkíyèsí wa. Àkíyèsí tí a tún ṣe níbi ìmúra wọn níbi orin yìí ni pé yàtọ̀ sí pé gbogbo àwọn ìyá náà ro ìró àti bùbá tó jẹ́ aṣọ ìbílẹ̀ Yorùbá, gbogbo wọn pátápátá ni wọ́n da ìborùn bo orí wọn èyí tó ṣàfihàn gbogbo wọn pátápátá pé ẹlẹ́sìn Ìsìláàmù ni wọ́n ní ìdílé ọba Ìlọrin. Olóri orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin tún fi yé wa pé tí ọmọ-ọba Ìlọrin tó jẹ́ obìnrin bá fẹ́ ọkùnrin àjèjì tí kì í ṣe láàrin mọ̀lẹ́bí ọba, yóò wá sí ààfin tàbí agbègbè ààfin kí àwọn tó lè ṣe ayẹyẹ yìí fún un ni, kì í ṣe pé àwọn yóò lọ sí ibìkan láti lọ fi eré yìí yẹ́ ọmọ kankan sí.

Ìwádìí tún fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé láàrin ara wọn ni wọ́n ti máa ń fẹ́ ara wọn gẹ́gẹ́ bí àṣà Fúlàní àti ẹ̀sìn Ìsìláàmù tí wọ́n ń tẹ̀lé ṣe gbà á láàyè. Ìyẹn ni pé ọkọ àti ìyàwó tí wọ́n bá kọrin yìí fún

máa ń jẹ́ ọmọ ìdílé ọba Ìlọrin lọ́pọ̀ ìgbà. Gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ, ọmọ ọba àná lè fẹ́ ọmọ ọba ìjẹta; ọmọ ẹ̀gbọ́n tó ti jìnnà síra wọn díẹ̀ lè fẹ́ ara wọn níwọ̀n ìgbà tí wọn kò bá ti jẹ́ ọmọ ìyá tàbí ọmọ bàbá kan náà, tí wọn kò sì jọ mu ọmú kan náà rí. Àwọn obìnrin tó jẹ́ ìyàwó ilé ọba Ìlọrin tàbí ọmọ-ọba Ìlọrin ló máa ń kọ orin yìí láti fi yẹ́ ọkọ tàbí ọmọ wọn sí pàápàá jù lọ lásìkò tí wọ́n bá ń ṣe ìgbeyàwó èyí tó jẹ́ ayẹyẹ tó gbajúmọ̀ jùlọ tí wọ́n fúnka mọ́ láwùjọ àwọn Ìlọrin.

## Tíọ́rì Àmúlò

Tíọ́rì méjì pàtàkì tí a lérò pé wọ́n bá iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí mu ni a lò láti ṣe àtúpalẹ̀ rẹ̀. Àwọn náà ni Tíọ́rì Ìmọ̀-Ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ àti Tíọ́rì Ajẹmọ́-Àṣà-Ìbílẹ̀/Tíọ́rì Ìfojú-Àṣà-Ìbílẹ̀-wò. Ìdí tí a fí lò wọ́n papọ̀ ni pé ìbágbépọ̀ ẹ̀dá tí a tún lè dà pè ní àṣùwàdà ló ń bí orin kíkọ nínú àwùjọ, bẹ́ẹ̀ náà sì ni ọ̀kan nínú àṣà ìbílẹ̀ tó gbajúmọ̀ nílẹ̀ Adúláwọ̀ ni orin jẹ́ nítorí pé gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ ló ní orin kọ̀ọ̀kan tó bá wọn mu pàápàá jùlọ nílẹ̀ Yorùbá.

### *Tíọ́rì Ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbé-pọ̀*

Ọ̀kan pàtàkì lára tíọ́rì tó gbajúmọ̀ láti yẹ iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ wò ni tíọ́rì ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ jẹ́. Èyí kò déédé rí bẹ́ẹ̀. Ìdí pàtàkì tó fà á ni pé gẹ́gẹ́ bí orúkọ rẹ̀, láìsí ìbágbépọ̀ ẹ̀dá, kò sí ohun tí à bá máa pè ní lítíréṣọ̀, nítorí pé èso àwùjọ ni lítíréṣọ̀ jẹ́. Lára ìbágbépọ̀ àti ìgbòkè-gbodò ọmọ èniyàn lójoojúmọ́ ló ń bí iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ yálà àwọn apohùn láwùjọ ni tàbí àwọn òǹkọ̀wé lítíréṣọ̀ láwùjọ. Ohun tó bá ń lọ láwùjọ náà ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ tí ó máa ń bí ìronújinlẹ̀ lórí rẹ̀ láti wá fi àrògún gbé e kalẹ̀, yálà lọ́nà ìpohùn tàbí ìlànà àkọsílẹ̀. Nítorí náà, tíọ́rì yìí ni a lè pè ní kàríìlé

tí kò fẹ́rẹ̀ẹ́ sí iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ tí kò ṣe é yẹ̀wò bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó lè má jẹ́ gbogbo rẹ̀ ni yóò lè yẹ̀wò fínnífínní láìṣe àlòpọ̀ rẹ̀ pẹ̀lú tíọ́rì mìíràn kí iṣẹ́ náà lè kẹ́sẹjárí dáadáa.

Barber (1979: 1) sọ pé: "Sociology is a way of trying to understand society, its structure, how it works, the forces that bring about changes in it". (Ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ jẹ́ ìgbíyànjú láti ní ìmọ̀ nípa àwùjọ, ìhun rẹ̀, bó ṣe ń ṣiṣẹ́ àti àwọn ohun tó ń mú àyípadà bá a). Àrífàyọ ohun tí Barber ń sọ ni bí tíọ́rì ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ ṣe jẹ́ pátàkì láti ní òye tó kún nípa àwùjọ, láti wa egbò àwọn ọ̀rọ̀ àwùjọ dé ìsàlẹ̀ àti láti mọ àwọn ohun tó lè mú àyípadà bá àwùjọ.

Nínú èrò tirẹ̀ náà nípa ìmọ̀ ìbára-ẹni-gbé-pọ̀, Akìwọwọ (1986: 114) sọ pé "sosiọ́lọ́jì jẹ́ ẹ̀kọ́ nípa bí àwọn ènìyàn ti ṣe ń gbé pọ̀". Ìyẹn ni pé ọ̀rọ̀ nípa ìbágbépọ̀ ẹ̀dá nínú àwùjọ ọmọ ènìyàn ló ń jẹ́ sosiọ́lọ́jì tó jẹ́ èdè àyálò láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì. Nínú iṣẹ́ rẹ̀ yìí náà ló ti fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé a lè tú ìbára-ẹni-gbé-pọ̀ sí àṣùwà tàbí àṣùwàdà èyí tó ń túmọ̀ sí pé àjèjé ọwọ́ kan kò gbẹ́rù dórí, àti wí pé òṣùṣù ọwọ̀ nìkan ló lè gbálẹ̀ tí yóò fi mọ́. Ìyẹn ni pé ìbágbépọ̀ tàbí ìṣùwà ni ẹ̀dá fi lè da nǹkan nínú àwùjọ tí ó di àṣùwàdà.

Nínú èrò tirẹ̀, Ògúnṣínà (1987: 19) gbà pé:

> Literature is concerned with men and his society. It is an art composed of words in such a way that it proffers entertainment, enlightenment and relaxation. It attempts to develop, elevate, expand and transform the experience of its audience.
>
> Lítíréṣọ̀ dá lórí àwọn ènìyàn àti àwùjọ. Iṣẹ́-ọnà tí a sẹ̀dá pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ lọ́nà tó fi lè dánilárayá, tọ́nisọ́nà

> àti múnigbafẹ́ ni. Ó máa ń gbìyàjú láti mú ìtẹ̀síwájú, ìdàgbàsóke àti àyípadà bá ìrírí àwọn olùgbọ́.

Ohun tí èrò Ògúnṣínà yìí ń ṣàlàyé fún wa ni pé lítíréṣọ̀ àti àwùjọ wọnú ara wọn bí òwú àwọ̀n ni. Èyí ni pé ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ náà ni ó ń bímọ tí a ń pè ní lítíréṣọ̀.

***Tíọ́rì Ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀ wò***

Ọ̀rọ̀ nípa àṣà ló jẹ́ ohun tó múmú láyà àwọn onímọ̀ nípa tíọ́rì yìí. Onírúurú ohun tó ṣodo sínú àṣà tàbí ohun tó bá ṣúyọ nípa àṣà ni wọ́n ń wá ọ̀nà àbáyọ fún. Nítorí náà, gẹ́gẹ́ bí àkòrí iṣẹ́ yìí tí a yàn láàyò tó jẹ́ orin ìbílẹ̀ Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin, tí a bá ṣe àmúlò tíọ́rì yìí náà láti yẹ iṣẹ́ náà wò, yóò mú kí iṣẹ́ náà kógo já dáadáa, nítorí pé ọ̀rọ̀ àṣà ìbílẹ̀ kò ṣe é já kúrò tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa orin ìbílẹ̀. Àṣà yìí kan náà ni a tún lè dà pè ni ìṣẹ̀ṣe. Àṣà tàbí ìṣèṣe yìí sì gbòòrò púpọ̀ nítorí ohun tó jẹ́ káríayé ni. Kò sí ẹ̀yà tó wà ní ayé yìí tí kò ní ìṣẹ̀ṣe tàbí àṣà tirẹ̀. Bí àwa Yorùbá ti ní, ni àwọn Ìgbò náà ni. Bẹ́ẹ̀ sì ni àwọn Háúsá ní pẹ̀lú àti gbogbo ẹ̀yà pátápátá nílẹ̀ Nàìjíríà. Àwọn Gẹ̀ẹ́sì, Faransé, Jámánì, Lárúbáwá, Ṣáínà (China), India àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ kò ṣàìní àṣà tiwọn náà pẹ̀lú. Nítorí náà, àṣà kálukú kàn lè yàtọ̀ láti ibi kan sí ibì èkejì ni.

Ọlátúnbọ̀sún (1979: 313) sọ nípa àṣà pé:

> Àṣà jẹ́ ìmúgbòòrò agbára ọmọnìyàn ní tọgbọ́n orí, ní tara àti ní ti ẹ̀mí, nípa ìkẹ́kọ̀ọ́ àti ìrírí. Àwọn ẹ̀rí àṣà àwọn ènìyàn máa ń jẹyọ nínú iṣẹ́-ọnà, orin, òfin, ẹ̀kọ́ nípa ìbálòpọ̀ ẹ̀dá àti ti ìṣèlú, ẹ̀sìn àti ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ sáyẹ́ǹsì.

Èrò Ọlátúnbọ̀sún yìí tọ́ka sí pé àṣà kó ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan sínú nípa àwùjọ. Ó jẹ́ ohun tó gbòòrò púpọ̀. Gbogbo ohun tí ó sì máa ń

ṣẹlẹ̀ ní àwùjọ nínú ìgbé ayé ojoojúmọ́ wọn bí i iṣẹ́-ọnà, orin, òfin, ẹ̀kọ́ ìbálòpọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ wà lára ohun tó wà lábẹ́ ohun tí a ń pè ní àṣà.

Gẹ́gẹ́ bó ṣe wà nínú Okafor and Emeka (2004: 12), oríkì tí Gustav Klamn fún àṣà ní: "The customs, information and skill, domestic and public life in peace and war, religion, science and art manifest in the transmission of past experience to the new generation". (Ìṣẹ̀dálẹ̀, ìròyìn àti agbára ìmọ̀ọ́nṣe, ìgbésí ayé ìkọ̀kọ̀ tàbí ti gbangba lásìkò àlàáfíà tàbí ogun, ẹ̀sìn, ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ sáyẹ́ǹsì àti iṣẹ́-ọnà tó ń ṣàfihàn àtagbà ìmọ̀ àtijọ́ sí tòde òní). Àkíyèsí nípa ohun tí Gustav sọ yìí ni pé àṣà àwùjọ jẹ́ ohun tó gbòòrò gan-an èyí tó ń ṣàfihàn ohun tí àwùjọ máa ń dúró lé gẹ́gẹ́ bí ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀.

"Culture is the characteristics of a particular group of people, defined by everything from language, religion, cuisine, social habits, music[1]". (Àṣà jẹ́ àbùdá àwọn ẹ̀yà kan ní pàtó, tó wà ní ìbámu pẹ̀lú gbogbo nǹkan bí i èdè, ẹ̀sìn, ìdáná oúnjẹ, ìṣesí láwùjọ, orin àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ).

> Culture refers to the cummulative deposit of knowledge, experience, beliefs, values, attitudes, meanings, hierachies, religion, notion of time, roles, spatial relations, concepts of universe and material objects and possessions acquired by a group of people in the course of generations through individual and group striving.[2]
>
> Àṣà ni a lè pè ni àpapọ̀ ìmọ̀, ìrírí, ìgbàgbọ́, ohun tí a kà kún bàbàrà, ìṣesí, ìtumọ̀, ìpele ìṣepàtàkì, ẹ̀sìn, ìgbà, ìkópa, àjọṣepọ̀ láwùjọ, ojú àmúwayé àti àwọn nǹkan tí a lè fojú rí àti àwọn ohun tí àwùjọ ní nípasẹ̀ ìgbìyànjú àdáṣe àti àjọṣe.

Àrífàyọ láti inú fọ́nrán ayélujárá wọ̀nyìí náà ń ṣàfihàn bí ohun tí a lè pè ni àṣà ṣe kún fọ́fọ́ tó àti bí ó ti ṣe pàtàkì tó.

Lákòótán, ìṣàmúlò tíọ́rì méjèèjì òkè wọ̀nyí fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí ṣe pàtàkì nítorí pé ìbágbépọ̀ ẹ̀dá wà lára ohun tó ń bí orin kíkọ nínú àwùjọ. Láìsí àṣùwàdà ọmọ ènìyàn, orin kíkọ kò lè wáyé, bẹ́ẹ̀ ni kò lè sí ohun tí a ó máa pè ní ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé gan-an pẹ̀lú. Bí àwùjọ ṣe ń dàgbà sí i ni àwọn nǹkan ọ̀tun ń ṣẹlẹ̀. Àjọṣepọ̀ ojoojúmọ́ láàrin ọmọ ènìyàn kó ipa pàtàkì fún ìtẹ̀síwájú àṣà àti ìṣe wọn. Ohun tó fojú hàn gbangba ni pé orin jẹ́ èso tó hù jáde nínú àṣà àwùjọ, ó sì máa ń ṣàfihàn oríṣiríṣi nǹkan tó ṣodo sínú àṣà. Lára àpẹẹrẹ èyí ni ẹ̀sìn, oúnjẹ, ìhùwàsí, ìgbéyàwó, ìkómọ, ìsìnkú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Níwọ̀n ìgbà tí ó sì jẹ́ pé àṣà, ọ̀rọ̀ tàbí ìṣẹ̀ṣe máa ń kún inú àwọn orin ìbílẹ̀, a wò ó pé ìka tí ó bá tọ́ sí imú ló yẹ ká fi ro imú.

## Àgbéyẹ̀wò Orin ní Ilẹ̀ Yorùbá

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ ló ti ṣiṣẹ́ lórí orin nílẹ̀ Yorùbá. Oríṣiríṣi ọ̀nà ni kálukú yà sí lórí ìwádìí wọn nípa oríṣìí orin tó wà nílẹ̀ Yorùbá. Ojú tí kálukú sì fi wo orin àti irúfẹ́ orin tí wọ́n gbé iṣẹ́ ìwádìí wọn lé lórí jẹ́ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. A rí àwọn tó gbé iṣẹ́ ìwádìí wọn lé orin ìbílẹ̀; àwọn mìíràn ṣiṣẹ́ lórí oríkì orin àti ìpínsísọ̀rí orin nígbà tí àwọn mìíràn fúnka mọ́ ìlò orin tí a tún lè pè ní ìwúlò orin. Ẹ̀wẹ̀, àwọn mìíràn ṣiṣẹ́ lórí orin ẹ̀fẹ̀, orin ètùtù, orin ayẹyẹ, orin ẹ̀sìn ìgbàlódé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Oríṣiríṣi orin ló wà nílẹ̀ Yorùbá gẹ́gẹ́ bó ṣe wà káàkiri ilẹ̀ Adúláwọ̀ àti lágbàáyé lápapọ̀. Oríṣìí àwọn onímọ̀ tàbí olùwádìí ló sì ti ṣiṣẹ́ lóríṣiríṣi ọ̀nà láti wá fìn-ín-ìn ìdí kókò débi tí ojú oníkálukú tó nípa onírúurú àwọn orin náà. Lára àwọn orin ilẹ̀

Yorùbá ni a ti rí orin bíi orin Àpàlà, Wéré, Fújì, Àdàmọ̀, Dadakúàdá, Wákà, Ọpa, Sákárà, Ìwéréǹde, Jùjú, Ìrègún, Ṣùkú Èwe, Bàlúù, Ẹlẹ́wẹ, Àpíírì, Aárè, Ìgbo, Àwúrèbe, Pàkenke, Sẹnwẹlẹ, Kèǹgbè, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Bí ẹyẹ ṣe ń lọ ni a ń sọ̀kò rẹ̀ àti pé ohun tí ó kọjú sí ẹnìkan ẹ̀yìn ló kọ sí ẹlòmíràn ni ọ̀rọ̀ ayé. Bẹ́ẹ̀ gẹ́lẹ́ ni ọ̀rọ̀ ojú tí àwọn onímọ̀ fi wo orin lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan lágbàáyé lápapọ̀. A rí i fàyọ pé a kò lè fún orin ní oríkì tàbí ìtumọ̀ kan pàtó nítorí pé ojú ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni kálukú fi wò ó. Ìhà tí kálukú sì kọ sí ìtumọ̀ orin yàtọ̀ síra wọn. Gẹ́gẹ́ bí ohun tí a rí fàyọ lórí ẹ̀rọ ìtàkùn àgbáyé, ọ̀nà mẹ́fà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni oríṣìí ìtumọ̀ tí àwọn kan fún orin pín sí. Àwọn náà ni:

1. Music is science - orin jẹ́ ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ sáyẹ́ǹsì.
2. Music is mathematical - orin jẹ́ ìṣirò.
3. Music is foreign language - orin jẹ́ èdè àjèjì.
4. Music is history - orin jẹ́ ìtàn.
5. Music is physical education - orin jẹ́ ẹ̀kọ́ ajẹmọ́-eré-ìdárayá.
6. Music is art - orin jẹ́ iṣẹ́-ọnà.

Àwọn tó pe orin ní ìmọ̀ sáyẹ́ǹsì jẹ́ àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ nípa orin tí wọ́n ní àtẹ ibi tí wọ́n kọ orin sí àti àwọn àmì ìdámọ̀ tó dúró fún ìgbóhùnsókè àti ìgbóhùnsódò orin náà. Ìgbàgbọ́ àwọn tó túmọ̀ orin sí ìṣirò náà ni pé orin ní àwọn ìgbésẹ̀ dọ́gba-n-dọ́gba tí a sì lè gbé e lé ìwọ̀n àsìkò lórí ìwé. Àwọn tó pe orin ní èdè àjèjì náà gbára lé pé gbogbo àwọn àmì tó jẹmọ́ orin lórí ìwé jẹ́ ti èdè Ítálì, Jámánì àti Faranṣé, tí kìí ṣe Gẹ̀ẹ́sì rárá ṣùgbọ́n tó jẹ́ àmì awo. Tí a bá tún wo èrò àwọn tí wọ́n pé orin ní ìtàn, ohun tó jẹ́

ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ èrò tiwọn ni pé orin máa ń sọ nípa àwùjọ tí a ti ń kọ ọ́, ó le sọ nípa ẹ̀yà, ìran tàbí orílẹ̀-èdè lápapọ̀. Ìyẹn ni pé ìtàn àwùjọ tí a ti ń kọ orin kan pàtó wà lára ohun tí orin náà máa ń fúnka mọ́ jù.

Síwájú sí i, ohun tí èrò àwọn tó pe orin ní ẹ̀kọ́ ajẹmọ́-lílo-ẹ̀yà ara gùnlé ni wí pé tí akọrin bá ń kọrin yóò máa ṣàmúlò gbogbo ẹ̀yà ara pátápátá bí i ìka, ọwọ́, apá, ètè, èrìgì àti gbogbo ẹ̀yà ara láti lè ṣe àgbékalẹ̀ orin náà kó lè dára kó sì wu etí í gbọ́. Àbùdá kẹfà tí wọ́n sọ pé orin ní ni wí pé iṣẹ́-ọnà ni orin. Ìyẹn ni pé orin jẹ mọ́ àtúndá. Gbogbo èrò òkè yìí ń fi yé wa pé àbùdá orin pọ̀ bẹ́ẹ̀ ni oríkì rẹ̀ sì kẹnú.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ ló ti ṣe ìgbìyànjú oríṣiríṣi lórí orin Yorùbá. Lára wọn ni a ti rí àwọn tó fún orin ní oríkì, ìtumọ̀ tàbí ṣàlàyé nípa rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ojú ti wọ́n fi wò ó. Lára wọn ni a ti rí Beier (1956), Dáramọ́lá àti Jéjé (1967), Akínjógbìn (1969), Ògúnpòlú (1975), Ọlátúnjí (1984), Ilésanmí (1985), Rájí (1987), Shébà (1988), Agbájé (1995), Ajíbóyè (2003), Ajíbádé (2005), Awólúsì (2012), Ọláwálé (2013) àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ mìíràn. Lára ìwòye oníkálukú wọn ni a ti rí ojú tí kálukú wọn fi wo oríkì tí a lè fún orin. Kálukú ṣiṣẹ́ lórí orin lọ́nà ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ tí wọ́n sì fi ojú tí wọ́n fi rí orin hàn.

Nǹkan tó gbòòrò gbáà ni tí a bá wo ohun tí orin jẹ́ láwùjọ Yorùbá nítorí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan ló rọ̀ mọ́ ọn bíi ìlù lílù, ijó jíjó, ẹ̀fẹ̀ síṣe lójú agbo, àti onírúurú àwọn àyẹ́sí tí àwọn akọrin máa ń rí lọ́dọ̀ àwọn olólùfẹ́ wọn tàbí òǹwòran. Lóòótọ́ ló jẹ́ pé ijó, ìlù àti orin máa ń rìn papọ̀, ṣùgbọ́n a sì lè rí àwọn orin ọ̀fọ̀ tàbí ti ètùtù tí kò nílò kí a jó sí wọn. Gẹ́gẹ́ bí orin ṣe jẹ́ ọ̀kan pàtàkì tí kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá, onírúurú ààyè

ni orin ti máa ń jẹ jáde nínú ìgbésí-ayé ojoojúmọ́ láàrin àwọn ẹ̀yà Yorùbá. Nítorí náà, orin máa ń jẹ jáde lónírúurú ààyè bíi inú ilé, lóde, níbi iṣẹ́, níbi fàájì, níbi ẹ̀sìn àti níbi ayẹyẹ lóríṣìíríṣìí bí ìṣílé, ìgbéyàwó, ìsọmọlóókọ, ìwúyè, ìṣèlú, ìsìnkú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Èrò Scholes (1952: 540) gẹ́gẹ́ bó ṣe wà nínú Awólùsì (2012: 29) ni pé “song is a natural means of self expression”. Èyí túmọ̀ sí pé orin jẹ́ nǹkan àdámọ́ tí a fi máa ń gbé èrò ẹni síta. Ó fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé orin jẹ́ ìlànà tí a fi lè gbé èrò ẹni síta fún àwọn ènìyàn láti gbọ́.

Beier (1956: 23) nínú èrò tirẹ̀ nípa orin sọ pé:

> There is no occasion in Yorùbá life that is not accompanied by songs. Births, marriage, house warming, and funeral are all occasions for lyrical songs of great beauty. Everyday life is also accompanied by grade deal of impromtu singing, a kind of musical thinking, in which the singer puts everything to a tune which happens to pass through his head.
>
> Ko sí ayẹyẹ kan nínú ìgbésí ayé ẹ̀yà Yorùbá ti kò ní orin tó bá a mu. ìbíọ́mọ, ìgbéyàwó, ìṣílé àti ìsìnkú jẹ́ ayẹyẹ fún orin alárinrin. Nínú ìgbésí ayé ojoojúmọ́, orin máa ń jẹ jáde láìròtẹ́lẹ̀, bíi fífi orin ronú, nínú èyí tí ọ̀kọrin ti ń sọ gbogbo èrò tó ń fi orí rẹ̀ rò di orin.

Ohun ti Beier ń gbìyànjú láti fihàn ni bí orin ṣe jẹ́ pàtàkì tó láwùjọ Yorùbá tó fi jẹ́ pé kò fẹ́rẹ̀ẹ́ sì abala ìgbésí ayé Yorùbá tí kò ní orin tó rọ̀ mọ́ ọn. Ìyẹn ni pé lára ìgbésí ayé Yorùbá gan-an ni orin wà.

## Àwọn Ọ̀rọ̀ Ajẹmórin àti Ìtumọ̀ wọn

Lára àwọn òkùtẹ̀ ọ̀rọ̀ ajẹmórin ni a gbìyànjú láti ṣàyẹ̀wò wọn ní abala yìí gẹ́gẹ́ bí onírúurú àwọn ọ̀mọ̀ràn ti sọ̀rọ̀ nípa wọn. Àwọn òkùtẹ̀ ọ̀rọ̀ wọ̀nyí ni a lè pè ní ìyekan tàbí ọbàkan fún orin láàrin ọmọ ènìyàn. Lára àwọn òkùtẹ̀ ọ̀rọ̀ wọ̀nyìí ni "music", "song", "melody", "lyrics" àti "rhythm". Oríṣìí àwọn ọ̀rọ̀ abórinjọ wọ̀nyìí ni a lè máa ṣalábàápàdé nínú àpilẹ̀kọ yìí. Aáyan yìí yóò tún jẹ́ atọ́nà láti mú kí ohun tí a ń sọ lè tún yé wá sí i.

**Tìlùtìfọn (*Music*):** Tìlùtìfọn ni èdè ìperí fún 'music'. Bóyá ohun tí ó fa èyí ni pé kì í ṣe ẹnu lásán ló ń gbe orin jáde. Àkópọ̀ àwọn ohun èlò tí a lè lù, tí a lè fọn mọ́ lílo ohùn ẹnu ló ń gbé ohun tí a lè pè ní "music" jáde. Ẹ̀rí yìí náà jẹ jáde lára èrò Longman (1978:937) nígbà tó sọ pé 'music' ni: "the arrangement of sounds made by instruments or voices in a way that is pleasant, or exciting". Ìtumọ̀ èyí ni pé orin jẹ́ àgbékalẹ̀ àwọn ìró ohùn tí a fi oríṣiríṣi èròjà orin àti ohùn gbé jáde lọ́nà tí yóò fi dùn tí yóò sì wu etí í gbọ́. Ìwé atúmọ̀ Hornby (2010:973) sì túmọ̀ 'music' sí "sounds that are arranged in a way that is pleasant or exciting to listen to. People sing music or play it on instrument". (Àwọn ìró ohùn tí a ṣètò lọ́nà tí yóò fi dùn mọ́ni tàbí wọni lára láti lè tẹ́tí sí i. Àwọn ènìyàn lè kọ músíìkì pẹ̀lú ẹnu lásán tàbí kí wọ́n fi ohun èlò orin kọ ọ́). Bámgbóṣé (1984) sọ pé músíìkì náà ni "music". Èrò yìí náà sì ṣe déédé pẹ̀lú ti Bánjọ (1990) nígbà tí òun náà sọ pé 'Music' ni músíìkì tàbí ẹ̀kọ́/ìmọ̀ nípa orin àti ìlù. Àrẹògún (2011) ní tirẹ̀ sọ wí pé "Music is just about sound and beats to be played and enjoyed" Ìyẹn ni pé músíìkì jẹ́ gẹ́gẹ́ bíi àdàpọ̀ ìró ohùn àti ìlù èyí tí

gbígbọ́ rẹ̀ yóò mú ìgbádùn wá. Lákòótán, kókó ohun tí a rí fàyọ ni wí pé ohun tí a lè pè ní 'music' kì í ṣe orin ẹnu lásán, ó jẹ́ àdàpọ̀ ohùn ẹnu, ìlù, ohun fífọn àti àwọn onírúurú àwọn èròjà orin mìíràn tó lè kórapọ̀ èyí tí yóò wá já sí tìlùtìfọn.

**Orin (*Song*):** Onírúurú àwọn onímọ̀ náà ló ti fèrò ọkàn wọn hàn nípa ohun tí a lè pè ní "song". Ìwé atúmọ̀ èdè ti (CMS) (1913) wà lára àwọn tó pe "song" ní orin. Àwọn mìíràn tó tún pè é bẹ́ẹ̀ ni Bámgbóṣé (1984), Longman (1978) àti Bánjọ (1990). Hornby (2010: 1419) pe "song" ní "a short piece of music with words that you sing" (Orin kúkúrú nínú tìlùtìfọn pẹ̀lú ọ̀rọ̀ tí a kọ jáde lẹ́nu). Ìyẹn jásí pé ohun tí a kọ jáde lẹ́nu là ń pè ní orin, ó yàtọ̀ sí 'music' tí a pè ní tìlùtìfọn èyí tó tún lè ṣàmúlò àwọn irin-iṣẹ́ oríṣìíríṣìí lílù tàbí fífọn èyí tí a fi sọ ọ́ lórúkọ (tìlùtìfọn). Kíkọ láti ẹnu nìkan ni orin.

**Adùn (*Melody*):** Longman (1995: 854) nínú èrò tirẹ̀ sọ pé: "Melody is a song or tune, the main tune in a complicated piece of music, the arrangement of musical notes in a way that is pleasant to listen to". Èyí tútọ̀ sí pé 'Melody' ni orin tàbí ohùn orin, olúborí ohùn tó hànde láàrin orin tó dàpọ̀, ìtò-lọ́wọ̀ọ̀wọ̀ àwọn àmì orin lọ́nà tó wuyì tí yóò fi dùn láti gbọ́ létí. Hornby (2010: 925) náà tún pe 'melody' ní "a tune, especially the main tune in a piece of music written for several instruments or voices". (Ohùn orin pàápàá jùlọ olúborí ohùn orin tí a ṣàkọ́ọ̀lẹ̀ rẹ̀ nínú tìlùtìfọn fún onírúurú èròjà orin àti ohùn). Hornby (2010: 925) tún tẹ̀síwájú nígbà tó tún túmọ̀ rẹ̀ pé "a piece of music or a song with a clear or simple tune" (tìlùtìfọn tàbí orin

tí ohùn orin rẹ̀ já gaara tí kò sì rújú). Ó sì tún kì í síwájú sí i nígbà tó tún pè é ní "the arrangement of musical notes in a tune" (ètò lọ́wọ̀ọ̀wọ́ àkọ́ọ̀lẹ̀ orin nínú ohùn orin). Gbogbo atótónu àti ìtumọ̀ wọ̀nyìí náà ń ṣàfihàn pé adùn orin ni 'melody' náà ni.

**Ọ̀rọ̀ Orin (*Lyrics*):** Ohun tí Longman (1995: 854) pe "Lyrics" ni "The words of song, especially a modern popular song" (Ọ̀rọ̀ inú orin ní pàtàkì jùlọ àwọn orin ìgbàlódé tó gbajúmọ̀). Ìtumọ̀ tí Wikipedia náà fún "lyrics" ni "set of words that make up a song, usually consisting of verses and choruses" (Àwọn ọ̀rọ̀ tó sùpọ̀ di orin pàápàà jù lọ èyí tó dá lérí ẹsẹ àti ègbè orin). Nínú èrò tí Hornby (2010: 891) oríkì tó fún 'lyrics' ni "(of poetry) expressing a person's personal feelings and thoughts, ... connected with, or written for singing". Ìtumọ̀ èyí ni pé (ajẹméwì) ìfèrò-ọkàn-ẹni àti ìrònújinlẹ̀ han... tó lájọṣepọ̀ pẹ̀lú, tàbí tí a kọ sílẹ̀ fún orin kíkọ. Àrífàyọ èrò tirẹ̀ yìí náà kò yẹ̀ lórí pé ọ̀rọ̀ orin ni 'lyrics' jẹ́ nítorí pé nígbà tí a bá ronú jinlẹ̀ lórí nǹkan tàbí ìhà tí a kọ sí nǹkan ni a tó máa ń fi ọ̀rọ̀ orin gbé e jáde fún aráyé gẹ́gẹ́ bí ìgbà tí a lóyún ọ̀rọ̀ tí a sì bí i fún aráyé gbọ́. A sì tún rí i gbámú pé 'lyric' jẹ́ àtòjọ ọ̀rọ̀ tí a mọ̀-ọ́n-mọ̀ kọ sílẹ̀ láti fi gbé orin jáde tàbí kọ ọ́ lórin ni.

**Ìwọ́hùn (*Rhythm*):** Ìtumọ̀ tí ìwé àtúmọ̀ *The New Havard Dictionary* fún "rhythm" gẹ́gẹ́ bó ṣe hàn nínú Vidal (2003: 1) ni "everything pertaining to the temporal quality or duration of musical sound". Èyí ni gbogbo ohun tó jọ mọ́ àwòmọ́ adùn eréfèé tàbí àkókò nípa ohùn orin.

Ẹ̀wẹ̀, nínú Vidal (2003: 1) kan náà ló tún ti hàn pé oríkì ti ìwé atúmọ̀ *Oxford Dictionary* Hornby (1973) fún rhythm ni "regular succession of weak and strong stresses, accents, sounds or movement in speech, music, dancing, etc." (tẹ̀léǹtẹ̀lé tó ṣe déédé nípa ìtẹnumọ́, ìsọwọ́sọ̀rọ̀, ìró tàbí gbígbé ọ̀rọ̀-ẹnu, orin, ijó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ jáde. Tí a bá tún fojú mìíràn wo ọ̀rọ̀ nípa 'rhythm', ìtumọ̀ tààrà tí èdè ìperí Yorùbá, Bámgbóṣé (1992) fún un ni 'ìwọ́hùn'. Lábẹ́ ìwọ́hùn ni a tún ti rí ìpèdè bíi 'antiphonal rhythm' èyí tó túmọ̀ sí ìwọ́hùn elégbè; 'rhythm segment' náà túmọ̀ sí ẹka ìwọ́hùn; 'rhythm unit' túmọ̀ sí ìdì ìwọ́hùn nígbà tí "rhythmic structure" túmọ̀ sí ètò ìwọ́hùn. Nínú èrò Hornby (2010: 1269), oríkì ṣókí tó fún 'rhythm' ni "a strong regular repeated pattern of sounds or movements. Èyí túmọ̀ sí ìlànà ohùn tó rinlẹ̀ dòdò ti a tẹpẹlẹ tàbí tẹnu mọ́ nínú orin. Lákòótán, tí a bá wo gbogbo atótónu àwọn ọ̀mọ̀ràn òkè wọ̀nyí lọ́kan-ò-jọ̀kan, ohun tí a lè rí fàyọ náà ni pé "rhythm" tí a lè tú sí ìwọ́hùn ní ṣókí kó ipa pàtàkì nínú orin.

## Àwọn Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ Ìgbàlódé àti Ìwúlò wọn fún Ìdàgbàsókè Orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin

Onírúurú ni àwọn àǹfààní tí ìgbàlódé àti ìmọ̀ ẹ̀rọ ti ṣe ní ìrọ̀rùn lóde òní nípa ìlànà tí a ń gbà bá ara wa sọ̀rọ̀. Èyí jẹ́ àǹfaàní nítorí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn nǹkan tó ti jìnnà sí ẹgbàágbèje ènìyàn tẹ̀lẹ̀tẹ̀lẹ̀ ló ti sún mọ́ wọn pẹ́kípẹ́kí nítorí àwọn ohun èlò igbàlódé náa. Ṣé Yorùbá bọ̀ wọ́n ní bí ẹyẹ ṣe ń lọ là ń sọ̀kò rẹ̀, ajá ìwòyí náà ló sì mọ ehoro ìwòyí lé, bẹ́ẹ̀ sì ni bí ayé ṣe ń yí náà ni kálukú ń bá ayé yí. Ìdí nìyí tó fi jẹ́ pé àwọn onírúuru ohun èlò ìbánisọ̀rọ̀ òde-òní ní àwọn ipa pàtàkì tí wọn ń kó ní àwùjọ wa

pàápàá jùlọ ìgbélárugẹ ati ìtànkálẹ̀ àwọn nǹkan àṣà ibílẹ̀ wa èyí tí ìpohùn jẹ́ ọ̀kan gbòògì láàrin wọn. Tẹ̀lẹ̀tẹ̀lẹ̀ kí ó tó di pé ẹ̀rọ gbohùn-gbohùn amóhùn-bú-gbẹ̀mù dé, tí àwọn apohùn ìbílẹ̀ bá ń ṣeré, gbogbo agbára ni wọn yóò fi máa sọ̀rọ̀ sókè kí àwọn òǹwòran wọn lè máa gbọ́ wọn dáadáa, ṣùgbọ́n èyí kò rí bẹ́ẹ̀ mọ́ lóde òní nítori ìgbàlódé ti sọ nǹkan di ìrọ̀rùn. Ẹni tó wà ní ọ̀nà jínjìn lè ní àǹfààní láti máa gbọ́ ohùn orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin níbi tó wà.

Tí wọ́n bá fẹ́ pe àwọn olórin yìí láti wá ṣeré fún ọmọ ọba kan láyé ọjọ́hun, ọgọ́rùn-ún obì ni wọn yóò fi ránṣẹ́ sí wọn láti fi pè wọ́n láti wá ṣe eré. Obì yìí ni àwọn náà yóò pín ká ilé ọmọlọ́ṣú ọba Ìlọrin gbogbo láti sọ fún wọn pé òde wà àti ọjọ́ pàtó tí wọn yóò ṣe eré náà. Ṣùgbọn ní òde-òní bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n máa ń gba obì náà, ṣùgbọ́n ẹ̀rọ alágbèéká tẹlifóònù ti ń kó ipa pàtàkì tó jọjú láti sọ fún ara wọn pé òde wà, dípò tí wọn yóò máa fi obì ránṣẹ́ bíi ti ọjọ́un. Òde eré ni wọ́n ti máa ń sáábà pín obì náà lóde òní nítorí pé ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ti ṣèrànwọ́ fún wọn.

Síwájú sí i, tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀ àwọn tó bá lọ sí òde eré wọn ló máa ń ní ànfààní láti wo eré wọn, ṣùgbọ́n lóde òní, àwọn oríṣìí ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ti mú nǹkan rọrùn láti jẹ́ kí ẹni tí kò bá sí lójú agbo nígbà tí wọ́n ń ṣe é tún ní àǹfààní láti gbọ́ ọ tàbí wò ó nińú fọ́nrán. A lè rí i wò lóri ẹ̀rọ ayélujára òde-òní bíi “facebook”, “Whatsapp”,” Youtube”, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Gbogbo èyí náà ń mú kí orin náà tún gbajúmọ̀ sí i kí ó sì di mímọ̀ fún àwọn tí kò gbọ́ nípa rẹ̀ tẹ́lẹ̀. Wọ́n sì ń ti ipasẹ̀ bẹ́ẹ̀ gbádùn orin náà ní ọ̀nà jínjìn réré. Kódà ó mú àǹfààní wá, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ilé-ẹ̀kọ́ gíga tí wọ́n ń kọ́ nípa orin àti ijó sì máa ń lò ó lẹ́nu ẹ̀kọ́ wọn.

Ohun èlò ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé yìí tún mú àǹfààní tó pọ̀ wá fún àwọn tó bá ń ṣiṣẹ́ ìwádìí ìjìnlẹ̀ láti ká a silẹ̀, láti farabalẹ̀ gbọ́ ọ fún ìtúpalẹ̀ kíkún nípa àwọn onírúurú kókó-ọ̀rọ̀ tó ṣodo sínú rẹ̀. Nítorí náà, ipa pàtàkì tí àwọn ohun èlò ìbánisọ̀rọ̀ oriṣirísi tó wà lóde-òní ń kó nínú iṣẹ́ lámèètọ́ kò kéré rárá.

## Àwọn Èròjà Orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin

Gẹ́gẹ́ bí orin ìbílẹ̀ tó jẹ́ àrà-ọ̀tọ̀ ní àwùjọ Ìlọrin, orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin ní àwọn èròjà ìṣèré tó yà wọ́n sọ́tọ̀ sí àwọn orin mìíràn pátápátá. Lára àwọn èròja wọ̀nyìí ni a ti rí ìyá odó, igbá àdému, igbá wàrà, igbá ẹrù, àwọn igi gbọọrọ tí a fi ń lu igbá wọ̀nyẹn àti ìlù dùndún méjì.



Àwòrán 1: *Àwọn akọrin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin ní ojú-agbo eré wọn.*

Nínú àwòrán òkè yìí ni a ti rí àwọn ìyá àgbà tí wọ́n ń kọrin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin lórí ìjòkó, tí àwọn kan sì ń jó yíká wọn

pẹ̀lú ègbè orin náà. Lẹ́yìn olùwádìí tó jẹ́ ọkùnrin tó hàn nínú àwòrán náà, a ó rí i pé àgbàlagbà obìnrin ni gbogbo àwọn tó jẹ́ agbátẹ̀rù orin náà. Tí a bá rí àwọn ènìyàn mìíràn láàrin wọn, àwọn oninàáwó tàbí àwọn ẹbí Ọba tó wá fi owó yẹ́ wọn sí lójú agbo ni.



Àwòrán 2: *Àwòrán àwọn Akọrin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin àti àfihàn àwọn Ohun-Èlò Ìkọrin wọn*

Nínú àwòrán òkè yìí ni a ti rí àwọn ìyá arúgbó ní ìsọ̀rí-ìsọ̀rí níbi tí àwọn kan ti jókòó ní orí ẹní yíká igbá ẹrù ńlá tí wọ́n dojú rẹ̀ délẹ̀ tí wọ́n sì ń fi igi gbọọrọ lù ú sí orin náà. Àwọn tó wà lápá òkè nínú àwòrán kan náà sì jòkó lórí àga yíká ìyá-odó ńlá méjì tí omi wà nínú wọn, tí wọ́n da igbá àdému dé wọn nínú tí wọ́n sì ń fi igi gbọọrọ lù wọ́n sí orin náà. Àyàn tó ń lu ìlù dùndún náà farahàn nínú àwòrán náà. Gbogbo èyí ń ṣàfihàn àwọn èròjà orin àti àwọn onílù orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin.

## Àbùdá-Àdámọ́ Orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin

Ọlọ́tọ̀ ní tòhun ọ̀tọ̀, báyìí náà ni ọ̀rọ̀ rí nípa orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin yìí. Ìdí ni pé àwọn àbùdá kan wà tó yà á sọ́tọ̀ sí àwọn irúfẹ́ orin mìíràn tó jẹ́ orin ìbílẹ̀ Ìlọrin. Lákọ̀ọ́kọ́, àwọn àgbàlagbà obinrin yálà ìyàwó tàbí ọmọ láti ìdílè Ọba Ìlọrin ni wọ́n máa ń kọ orin yìí tí Ọba Ìlọrin tàbí ọ̀kan nínú àwọn ọmọ Ọba Ìlọrin bá pè wọ́n fún eré.

Àbùdá mìíràn tún ni pé, gẹ́gẹ́ bí orin ìbílẹ̀ tó sì jẹ́ àso ní àwùjọ Ìlọrin, orin yìí ní àwọn èròjà ìṣèré tó yà wọ́n sọ́tọ̀ sí àwọn orin mìíràn pátápátá . Lára àwọn èròja wọ̀nyìí ni a ti rí ìyá odó, igbá àdému, igbá ẹrù, àwọn igi gbọọrọ tí a fi ń lu igbá wọ̀nyẹn àti ìlu dùndún méjì tí tí àwọn àgbà ọkùnrin méjì máa ń bá wọn lù sí orin náà, èyí tí ìwádìí fihàn pé kò tíì pẹ́ púpọ̀ tí wọ́n ṣe àfikún rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára èròjà orin náà nítorí pé wọn kì í lu dùndún sí i láti ìbẹ̀rẹ̀pẹ̀pẹ̀. Inú igbá àdému ti ìbílẹ̀ ni wọ́n sì máa ń pa owó tí wọ́n bá fi ń yẹ́ wọn sí lójú agbo sí. Àkíyèsí ni pé bóyá èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé ìran Fúlàní ni ìpilẹ̀ wọ́n kí wọ́n tó di Ìlọrin.

Síwájú sí i, orin ààfin ni orin yìí , èyí tó túmọ̀ sí pè wọn kì í kọ orín yìí tayọ gbogbo agboolé àwọn ìran Ọba Ìlọrin, tí gbogbo wọn kò jìnnà sí ààfin ọba. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mẹ́nu bà á lókè tẹ́lẹ̀, tí ẹbí ọba kan bá fẹ́ pè wọ́n sí òde, ẹni náà yóò mú obì ọgọ́rùn-ún wá sí ilé olórí. Obì yìí ni olórí yóò wá fi ránṣẹ́ káàkiri sí gbogbo àwọn obìnrin láti pésẹ̀ níbi ayẹyẹ náà.

Kókó pàtàkì mìíràn ni pé tí wọ́n bá ń kọrin yìí, àwọ́n tó ń gbe orin àti àwọn olóde máa ń jó pòòyì àwọn tó ń kọrin àti àwọn onílù pẹ̀lú onígbá ni. Ìlànà ìṣeré wọn lójú agbo yàtọ̀ sí àwọn orin yòókù ní Ìlọrin. Àbùdá mìíràn tó tún ṣe kókó ni pé àwọn tó bá jẹ́ ọmọ ọba Ìlọrin nìkan ni orin/eré yìí wà fún. Wọn kì í kọ ọ́ fún ẹni tí kò bá wá láti ìdílé ọba rárá.

## Àkíyèsí Ìjọra àti Ìyàtọ̀ orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin àti Igbá-Títí ní Ọ̀yọ́ Aláàfin

Àkíyèsí kan tí a ṣe pẹ̀lú orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin yìí ni pé ó ni àwọn àfijọ kan pẹ̀lú Orin Igbá-Títí ní Ọ̀yọ́ Aláàfin nípa àwọn ohun èlò ìkọrin wọn, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé a rí i pé àwọn ọ̀ṣọ́ọ́rọ́ adélébọ̀ ló wà nídìí orin Igbá-Títí Ọ̀yọ́ Aláàfin. Ìyàtọ̀ mìíràn tó tún wà níbi àwọn tó ń ṣeré Igbá-Títí ní Ọ̀yọ́ ni pé àwọn ṣí orí sílẹ̀ wọ́n sì fi ìlẹ̀kẹ̀ sọ́rùn àti ọwọ́ èyí tó ń ṣe àfihàn ìṣẹ̀ṣe Yorùbá, nígbà tí àwọn tó ń kọrin Ọlọ́mọ-Ọba ní Ìlọrin máa ń borí dẹ́dẹ́ẹ́dẹ́ èyí tó fi wọ́n hàn bí ẹlẹ́sìn Mùsùlùmí. A tún ṣàkíyèsí pé àtẹ́lẹwọ́ ni àwọn tó ń kọrin Igbá-Títí máa fi ń lu igbá wọn, ṣùgbọ́n igi ni àwọn tó ń kọrin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin máa fi ń lu igbá ní tiwọn.

Ọkùnrin kì í kọ orin yìí rárá, ó kàn jẹ́ pé àwọn ọkùnrin àgbà méjì máa ń lu ìlù àdàmọ̀ kún igbá tí wọ́n ń lù sí orin yìí ni.

Ìkópa ọkùnrin níbẹ̀ tún ni pé wọ́n máa darapọ̀ mọ́ àwọn obìnrin tó ń jó yípo àwọn tó jókòó tó ń kọrin. Èyí wà fún yíyẹ́ àwọn aláré sí bẹ́ẹ̀ wọ́n máa ń ná owó fún wọn. A tún máa ń rí ìkópa àwọn ọ̀sọ́ọ̀rọ̀ adélébọ̀ àti ọmọge lásíkò àyẹ́sí nípa jíjó yípo àti fifi owó níná sàyẹ́sí àwọn ìyá tó ń kọrin wọ̀nyìí nípa sísọ owó sínú igbá wọn.



Àwòrán 3: *Àwòrán tó ṣe àfihàn àwọn Akọrin Igbá-Tìtí ní Ọ̀yọ́ Aláàfin*

Nínú àwòrán òkè yìí ẹ̀wẹ̀, a rí i pé ìyá-odó tí wọ́n da omi sí nínú pẹ̀lú igbá wà níbẹ̀. A sì rí igbá ẹrù ní ilẹ̀ àti èyí tí wọ́n ti lù fọ́ lọ́wọ́ wọn; igi gbọọrọ tí wọ́n fi ń lu igbá náà wà lórí ẹní. Èyí fara jọ àwọn èròjà orin ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin bó tilẹ̀ jẹ́ pé igbá fínfín tí wọ́n ti ṣe lọ́ṣọ̀ọ́ ni tiwọn ní Ọ̀yọ́ láti ṣàfihàn iṣẹ́-ọnà igbá fínfín. Àkíyèsí tí a tún ṣe nípa àwòrán òkè yìí ni pé yàtọ̀ sí obìnrin kan tó dàgbà díẹ̀ láàrin àwọn akọrin yìí, àwọn ọ̀ṣọ́ọ̀rọ̀

adélébọ̀ ni àwọn yòókù, èyí tó yàtọ̀ sí àwọn akọrin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin tí wọ́n jẹ́ kìkìdá àgbàlagbà.

### Ìwúlò Orin Ọlọ́mọ-Ọba ní Ìlọrin

Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni orin yìí gbà wúlò pàápàá jùlọ ní àwùjọ Ìlọrin. Lára wọn ni a ti rí àwọn kókó tí a ṣàlàyé wọ̀nyí.

***Ìrántí àwọn Babańlá wọn:*** Lákọ̀ọ́kọ́, orin yìí wúlò fún ìrántí àwọn Ọba Ìlọrin tó ti wàjà títí tó fi dórí èyí tó wà lórí ìtẹ́. A lè rí àpẹẹrẹ èyí nínú àfàyọ orin Ọlọ́mọ-Ọba kan tó lọ báyìí:

| | |
|---|---|
| Lílé: Ẹ jẹ́ á kọ́ba | Ègbè: Ẹ jẹ́ á kọ́baa wa |
| Lílé: Àbú Sàlaamì | Ègbè: Àbú Sàlaamì |
| Lílé: Ẹ jẹ́ á kọ́ba wa | Ègbè: Ẹ jẹ́ á kọ́ba wa |
| Lílé: Ọbá wa Sítà | Ègbè: Ọbá wa Sítà |
| Lílé: Ẹ jẹ́ á kọ́ba | Ègbè: Ẹ jẹ́ á kọ́ba |
| Lílé: Ọ̀bá Sùbéérù | Ègbè: Ọ̀bá Sùbéérù |
| Lílé: Ẹ jẹ́ a kọ́ba wa | Ègbè: Ẹ jẹ́ á kọ́ ba wa |
| Lílé: Àlíyù Dòdó | Ègbè: Àlíyù Dòdó |
| Lílé: Ẹ jẹ́ á kọ́ba wa | Ègbè: Ẹ jẹ́ a kọ́ba wa |
| Lílé: Mọ́mọ-Lọsọ́ | Ègbè: Mọ́mọ-Lọsọ́ |
| Lílé: Ẹ jẹ́ á kọ́ba wa | Ègbè: Ẹ jẹ́ á kọ́ba wa |
| Lílé: Súlé mọ́ọ̀nà | Ègbè: Súlé mọ́ọ̀nà |
| Lílé: Àyìnlá Óníbudó | Ègbè: Àyìnlá Óníbudó |
| Lílé: Ẹ jẹ́ á kọba | Ègbè: Ẹ jẹ́ á kọba |
| Lílé: Àbùdù Kádírì wa | Ègbè: Àbùdù Kádírì wa |
| Lílé: Ẹ jẹ́ á kọba | Ègbè: Ẹ jẹ́ á kọ́ba wa |
| Lílé: Àtándá Òpó | Ègbè: Àtándá Òpó |
| Lílé: Ẹ jẹ́ á kọ́ba wa | Ègbè: Ẹ jẹ́ a kọba wa |
| Lílé: Sùlú Kànánì | Ègbè: Sùlú Kànánì |
| Lílé: Ẹ jẹ́ á kọ́bá wa | Ègbè: Ẹ jẹ́ á kọ́ba wa |

| | |
|---|---|
| Lílé: Àlábí Òpó | Ègbè: Àlàbí Òpó |
| Lílé: Ẹ jẹ́ á kọ́ba wa | Ègbè: Ẹ jẹ́ á kọ́ba wa |
| Lílé: Àlí bàbá Àgbà | Ègbè: Àlí Bàbá Àgbà |
| Lílé: Ẹ jẹ́ á kọ́ba wa | Ègbè: Ẹ jẹ́ á kọ́ba wa |
| Lílé: Ìṣọ̀lá Òpó | Ègbè: Ìsọ̀lá Òpó |
| Lílé: Arígbábuwó | Ègbè: Arígbábuwó... |

Àpẹẹrẹ orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin tó wà lókè yìí ń tọ́ka sí orúkọ gbogbo àwọn ọba mẹ́wẹ̀ẹ̀wá tó ti jẹ ní Ìlọrin títí tó fi dórí ọba kọkànlá tó wà lórí oyè lásìkò iṣẹ́ ìwádìí yìí. Èyí wúlò láti fìdí ìtàn tòótọ́ múlẹ̀ àti láti jẹ́ kí àwọn èwe ìwòyí mọ bí àwọn ọba náà ṣe jẹ tẹ̀léra wọn.

***Pàtàkì Ọmọ Láwùjọ:*** Ọmọ ṣe kókó, o sì ṣe pàtàkì láwùjọ Yorùbá. Yorùbá kì í fi ọ̀rọ̀ ọmọ bíbí ṣeré rárá, ìdí nìyí tó fi hàn nínú àwọn ìpèdè òwe wọn bí i: "bíná bá kú a feérú bojú; bọ́gẹ̀dẹ̀ bá kú a fọmọ rẹ̀ rọ́pò", "Ijọ́ á bá kú laṣọ dègbé, ọmọ ni ká rà".
A rí ìpèdè tó fi pàtàkì ọmọ bíbí hàn lóríṣiríṣi ní inú orin ìbílẹ̀ Ìlọrin. Àpẹẹrẹ kan nìyí láti inú ijó Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin pé:

Lílé: Ọmọ ni o yàn
Erí Aládùkẹ́ ọmọ ni o yàn, o tóó yanwó
Ègbè: Ọmọ ni ọ yàn
Erí Aládùkẹ́ ọmọ ni ó yàn, o tóó yanwó
Lílé: Ọmọ ni o yàn
Erí Aláduùnní ọmọ ni o yàn, ó tóó yanwó ó ó ...

Àyọlò orin òkè yìí ń tọ́ka sí i wí pé kí orí inú àwọn ìyàwó tí wọn ń kọrin ìbílẹ̀ fún yìí yan ọmọ kí wọ́n tó yan owó. Mímọ pàtàkì ọmọ bíbi ló jẹ́ kí wọ́n kọ orin báyìí nítorí pé bí

èèyàn bá wáyé tí kò bá bímọ láyé, ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé ẹni ọ̀hún pasán láyé ni. Bí ìgbà tí ejò kọjá lórí àpáta tí kò ní ipa ni.

***Ìrántí Ìṣẹ̀lẹ̀ Ọjọ́ Pípẹ́:*** Abdul-Salami II, Ọba Mọmọlọ́ṣọ̀ọ́ tó jẹ ọba karùn-ún ní Ìlọrin láàrin ọdún 1891 sí ọdún 1896 ní ìtàn fi yé wa pé láti ojú ogun tí wọn ń bá Ọ̀fà jà nígbà náà ( Ogun Adínimọ́lé) ni ipò ọba ti kàn án lẹ́yìn tí Ọba Àlíyù Wàjà ní Ìlọrin. Ojú ogun yìí náà ni àwọn Balógun mẹ́rẹ̀ẹ̀rin ti fara mọ́ ìyànsípò rẹ̀, tí wọ́n sì sìn ín wá sí Ìlọrin pẹ̀lú àwọn ẹmẹ̀wà tó tó ogún ẹgbẹ̀rún àti ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹṣin (Oníkòkò 1992: 16-17; Jímbà 2009: 130). Ìtọ́kasí èyí náà hàn nínú orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin kan tó lọ báyìí pé:

> Ọ̀fà ló ti móyèe o o o
> Ọ̀fà ló ti móyè
> Ọba wa Mọ́mọ́ òokú o o.
> Ọ̀fà ló ti moyé o o

Ohun tí wọn ń tọka sí pẹ̀lú orin yìí ni láti rán àwọn ènìyàn létí nípa ọ̀nà tí ọba yìí gbà dorí oyè. Èyí náà jẹ ìrántí fún àwọn ọmọ-ọmọ rẹ̀. Ó sì tún dà gẹ́gẹ́ bí ìforinsọ̀tàn èyí tó ṣàfihàn bí Ọba náà gan-an fúnraarẹ̀ ṣe jẹ́ Akọni Jagunjagun àti ìlúfẹ́milóyè tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn fẹ́ràn rẹ̀ tó fi di pé wọ́n wá gbé e sí orí ipò Ọba Ìlọrin.

Gbígbé àṣà lárugẹ àti àmúgbòòrò nǹkan àjogúnbá náà tún jẹ́ ìwúlò pàtàkì tí a lè rí tọ́ka sí nípa orin yìí. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pe orin yìí ti di àṣà kan pàtàkì láàrin àwọn ẹbí ọba Ìlọrin láti orí ọba kejì tó jẹ ní Ìlọrin títí di àsìkò yìí. Gbogbo ọmọ ọba Ìlọrin ló sì mọ pàtàkì orin yìí nínú ìdílé wọn, pàápàá jùlọ ẹni tí wọn kò bá tíì ṣe orò orin kíkọ yìí fún, ìgbéyàwó rẹ̀ kò tíì pé. Nítorí náà, nípa ṣíse èyí, amúgbòòrò ń bá orin yìí lóòrèkóòrè láwùjọ Ìlọrin

àtí lágbàáye lápapọ̀ pàápàá jùlọ nípasẹ̀ títẹ̀ ẹ́ sínú fọ́nrán tàbí sórí ẹ̀rọ ayélujára fún àǹfààní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn láti wò.

Ìwúlò mìíràn tí orin yìí tun ní ni pé ó jẹ́ okùnso fún ẹbí àwọn ọlọ́mọ-ọba Ìlọrin lápapọ̀. Èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé gbogbo àwọn ẹbí ọba Ìlọrin yálà tí wọ́n ń gbé nínú ìlú Ìlọrin tàbí ẹ̀yìn odi ni wọ́n máa ń ní àǹfààní láti tún fóju kan ara wọn. Nítorí náà, orin Ọlọ́mọ-Ọba Ìlọrin yìí máa ń mú àkójọpọ̀ tó ṣàǹfààní ṣẹlẹ̀ láàrin ara wọn tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ tí iṣẹ́ ajé ti mú kí wọ́n pẹ́ lájò darí wálé tí àwọn ọmọ wọn yóò sì tún dá ara wọn mọ̀ gẹ́gẹ́ bí ọmọ Ọba Ìlọrin.

Ẹ̀wẹ̀, okùnfà ọrọ̀ ajé tún ni orin yìí jẹ́ fún àwọn ìyá tó ń kọ orin náà nítorí pé bí wọ́n bá ń ṣeré yìí, wọ́n máa ń náwó fún wọn àti àwọn onílù wọn. Nípasẹ̀ báyìí, àwọn òṣèré wọ̀nyìí máa ń pín owó tó jọjú lọ sílé wọn pẹ̀lú ìdùnnú pé àwọn tún ń jẹ àǹfààní ńlá láti ara ṣíṣe eré ìbílẹ̀ tó jẹ́ àjogúnbá àwọn.

## Àgbálọgbábọ̀

A ti ṣe àgbéyẹ̀wò ipa ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé lórí ìdàgbàsókè orin ọlọ́mọ-ọba Ìlọrin. A rí i fà yọ pé lóòótọ́ ni orin náà jẹ́ orin ìbílẹ̀ ṣùgbọ́n onírúuru ipa ni ọ̀làjú ìgbàlódé ti ní lórí ìtànkálẹ̀ tàbí ìdàgbàsókè rẹ̀. A tún rí i pé wàhálà kí wọ́n máa pín obì kiri ilé àwọn ọmọlọ́ṣú ọba Ìlọrin nígbà tí wọ́n bá pe àwọn akọrin ìbílẹ̀ yìí láti wá ṣeré ni ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ìgbàlódé ti sọ di ìrọ̀rùn. Nípasẹ̀ ṣíṣe àmúlò ẹ̀rọ ìgbàlódé yìí, gbogbo wọn ni wọn á tètè gbọ́ káríkárí àti pé wọ́n tún máa ń gbọ́ irúfẹ́ ìkéde ìgbéyàwó bẹ́ẹ̀ lórí ẹ̀rọ rédíò àti móhùnmáwòrán. Iṣẹ́ yìí jẹ́ kí a tún rí i mọ̀ wí pé ipa tí kò lẹ́gbẹ́ ni ẹ̀rọ ayélujára bíi *Facebook*, *Youtube*, *Whatsapp* àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ń kó ninú ìdàgbàsókè orin yìí nítorí pé ohun tó jìnnà

sí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ló ti súnmọ́ wọn lóde òní nípa jíjù wọ́n sí orí ẹ̀rọ ìtàkùn àgbáyé fún ọ̀pọ̀ ènìyàn láti wò ó. Yàtọ̀ fún èyí, ọ̀nà ìbánisọ̀rọ̀ àti ẹ̀rọ ìgbàlódé ń kó ipa tó jọjú fún ìtúpalẹ̀ àti iṣẹ́ lámèétọ́ orin yìí. Lákòótán, gẹ́gẹ́ bó ṣe jẹ́ pé bí ẹyẹ ṣe ń lọ ni a ń sọ̀kò rẹ̀, a gbọ́dọ̀ máa tẹ̀síwájú láti máa ṣàmúlò àwọn nǹkan ìgbàlódé fún ìlọsíwájú àti ìmúgbòòrò àṣà àtayébáyé wa, kí a sì yàgò fún lílò wọ́n lọ́nà òdì èyí tó lè mú ìfàsẹ́yìn tàbí ìparun bá aṣa wa nílẹ̀ Adúláwọ̀.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Agbájé, J.B. (1995). " A Literary Study of Folksongs of the Èkìtì People of Nigeria". Unpublished Ph.D. Thesis. Department of Linguistics and Nigerian Languages, University of Ìlọrin, Ìlọrin.

Ajíbádé G.O. (2005). "Is there no Man with Penis in this Land? Erocticism and Performance in Yoruba Nuptial Song". *African Study Monographs* 26(2), 99-113.

Ajíbóyè, O. (2003). *Ewì Alohùn Yorùbá: Orin.* Ìlọrin: Majab Book.

Akínjógbìn, A. (1969). *Ewì Ìwòyí.* Glasgow:Collins Sons and Co. Ltd.

Akíwọwọ, A. (1986). "Àṣùwàdà Ènìyàn" in *IFẸ̀: Annals of the Institute of Cultural Studies,* University of Ifẹ̀, Nigeria No. 1. pp. 113-123.

Awólùsì, Y.A. (2012). "Àgbéyẹ̀wó Kókó-ọ̀rọ̀ àti Ìṣàmúlò-Èdè Inú Orin ìbílẹ̀ Èkìtì Fẹ́mi Àríyọ̀ àti Onílé-Ọlá Dahunsi" Ph.D. Thesis. Ilé-Ife: Obafemi Àwolowo University, Ilé-Ifẹ̀.

Bámgbósé, A. (1984). *Yorùbá Metalanguage.* Vol. I. Ìbàdàn: University Press Ltd.

Barber, K. (1979). "Oríkì Òkukù" Ph.D. Thesis, Ilé-Ifè: University of Ife, Ilé-Ifẹ̀.

Beier, H.U. (1956). "Yoruba Vocal Music". *Journal of the African Music Society,* Vol. 1, No. III, pp. 23-28.

Church Missionary Society. (1913). *A Dictionary of the Yorùbá Language.* Oxford: University Press Plc.

Dáramọ́lá, O. àti Jéjé, A. (1967). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press.

Hornby, A.S. (1973). *Advanced Current Dictionary of Current English.* London: Oxford University Press.

Hornby, A.S. (2010). *Oxford Advanced Learners' Dictionary of Current English.* Oxford: Oxford University Press.

Ilésanmí, T.M. (1985). "Hearthstones: A Cultural Study of Songs In Ìjèṣàland". Ph.D. Thesis, Department of Linguistics and Nigerian Languages, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn.

Jimba, A.S. (2008). *Portraits of Royalty: An Illustrated Spotlight on the 11th Emir of Ìlọrin*. Ìlọrin: Semaki Publishers (Nig.) Ltd.

Longman, (1995). *Longman Dictionary of Contemporary English.* Barcelona: Longman Group Ltd.

Longman, (1995). *Longman Dictionary of Contemporary English.* Barcelona: Longman Group Ltd.

Ògúnpolú, F. (1975). "Ọ̀kọ̀sí Festival Songs". *Yorùbá Oral Tradition,* Wande Abimbọla (ed.), Department of African Languages and Literature, University of Ifẹ̀, Ilé-Ifẹ̀. o.i. 551-598.

Ògúnṣíná, B. (1987). "The Sociology of the Yorùbá Novel: A Study of Isaac Thomas, D.O. Fágúnwà and Ọládẹ̀jọ Òkédìjí. Unpublished Ph.D. Thesis, University of Ìbàdàn.

Ọlátúnbọ̀sún, B. (1979), Odòlayé Àrẹ̀mú gẹ́gẹ́ bí Akéwì Yorùbá" B.A. Thesis, Department of Lingusitics and Nigeria Languages, University of Ìlọrin.

Ọlátúnjí, O. O. (1984). *Features of Yorùbá Oral Poetry.* Ìbàdàn: University Press Ltd.

Ọláwálé, H. (2013). "Àgbéyẹ̀wò Kókó-Ọ̀rọ̀ àti Ìṣọwọ́-lò-èdè inú orin Dadakúàdà Jáígbadé Àlàó ní Ìlọrin. Research Seminar, Department of Linguistics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Ọláwálé, H. (2015). Àgbéyẹ̀wò Orin Ìbílẹ̀ Yorùbá ní Ìlọrin. Ph.D. Thesis, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Onikoko, A.T. *A History of Ìlọrin Emirate.* Ìlọrin: Sat-Adis Press Service Enterprises. 1992. Print.

Rájí, S.M. (1987). "Orin Ọ̀tẹ̀". M. A. Thesis, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Sheba, J.O. (1988). "Orin Arẹmọ ní Ààrin Ifẹ̀ àti Ìjẹ̀ṣà" M.A. Thesis, Department of African Languages and Literatures, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Vidal, T. (2003). "Rhythm and Metre in Yorùbá Songs" in *Nigerian Music Review*, No 4, 1-16. Department of Music, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University.

## Ìtàkùn Àgbáyé

www.cwrl.utexas.edu.ng Retrieved on 18-6-2013

www.livescience.com Retrieved on 27-4-2014

## Ìtọsẹ̀ Ọ̀rọ̀

[1] www.live science.com retrieved on 27/4/2014.

[2] www.live science.com. retrieved on 27/4/2014.

[3] www.cwrl.utexas.edu.ng retrieved on 18/6/2013.